# ORIKI IYERU OKIN OLOFA MOJO

**Iyeru okin olofa mojo, olalomi omo abisujoruko, omo ijakan ijakan tiwon nja loffa nijosi, ebimi elo soju tani, osoju ebe lala, osoju poro ninu oko, osoju agbele yarara, iba soju oloko, iba lawon, omo buree, laare, ikan ogbodo jukan loffa, bikan ba jukan loffa ogun ni kowon rooro rooro, ogun oja kooko iran Baba temi ri, iyeru okin nimode nimo dasa lami-lapa, olalomi nimode nimo dasa lami-lobe, iyeru okin fesolami emaama je kapa mi ojin jojo, Offa oma aka, eru olofa loma aka, ori je nlowo, ori je nbimo, oosa je nla bi iyeru okin oloffamojo olalomi omo abisujoruko, omo odu meta loffa, okan ni kapa Erin nla, ko dokun, okan ni kapa agbo bolojo, ko dosa, okan ni kamu akuko gagara wa, eyi ta pa erin fun kole kodun, eyi ta pa agbo fun kole dosa, eyi tamu akuko gagara fun lodagunloko loffa, oun lodi afele omi ti gbogbo ayaba npon mu, ibi momoyin de ni makiyin de; Omo olalomi mopada seyin.**